Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras
São Francisco do Conde (BA) | vol. 5, nº Especial I | p. 235-242 | jan./ jun.2025.

# Àfihàn Ohun tí Ifá sọ Nípa Aṣàyàn Ẹranko Láwùjọ Yorùbá

# Revelando o que Ifá diz sobre a seleção animal na sociedade iorubá

**Fúnmiláyọ̀ Tèmítọ́pẹ́ ÀJÀYÍ, Ph.D** *
ORCID iD https://orcid.org/0009-0000-5218-4612

**ÀṢAMỌ̀**
Pàtàkì ni Ifá jẹ́ lára lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá.Awùjọ Yorùbá sì ní ìgbàgbọ́ púpọ̀ nínú rẹ̀. Kò sí ohun tí Ifá kò sọ̀rọ̀ lé lórí, bẹ̀rẹ̀ láti orí ọmọ ẹ̀dá ènìyàn, ìbáṣepọ̀ láàrin ọkọ àti aya, igi oko, òkè, odò, ilẹ̀, ewéko, ẹyẹ, kòkòrò, ìbágbépọ̀ ẹ̀dá, ìtàn àwọn òrìṣà àti àwọn ẹranko lóríṣiríṣi. Ifá sọ̀rọ̀ púpọ̀ lórí oríṣiríṣi àwọn ẹranko igbó, gbogbo àwọn ẹranko tí Ifá sọ̀rọ̀ nípa wọn ni ó fi pa òwe fún àwọn ọmọnìyàn. Ọ̀pọ̀ ìgbà ni Ifá sọ̀rọ̀ nípa àwọn ẹranko tí ó sì fi wọ́n hàn gẹ́gẹ́ bí ènìyàn. Bí àpẹẹrẹ wọ́n lè ní ìṣòro kí wọ́n lọ sí ọ̀dọ̀ Babaláwo kí wọ́n lọ dífá, kí ìṣòro wọn ó sì jẹ mọ́ ẹbọ rírú àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ifá kún fún oríṣiríṣi ìmọ̀ ìjìnlẹ̀. Ifá ni ó jẹ́ ká mọ̀ nípa ìtàn ìwáṣẹ̀ àwọn ẹranko, ó sì tún jẹ́ kí àwọn ọdẹ mọ orúkọ tí à ń pe àwọn ẹranko wọ̀nyí lóríṣiríṣi àti irú ipa tí wọ́n ń kó láwùjọ àwọn ènìyàn. Ohun tí iṣẹ́ yìí tẹpẹlẹ mọ́ jù lọ ni àfihàn ohun tí Ifá sọ nípa àwọn ẹranko. Bí o ṣe fi wọ́n hàn gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ọwọ́ Olódùmarè mìíràn láwùjọ. Àwọn ìsọ̀rí tí a gbé yẹ̀wò nínú iṣẹ́ yìí ni ìtàn àwọn ẹranko bí ó ṣe hàn nínú Ifá, àfihàn àwọn ẹranko nípa ìhùwàsí wọn àti ẹ̀kọ́ tí ó kọ́ àwùjọ.

**KÓKÓ ỌRỌ̀**
Lítírésọ̀ Alohùn,Ẹranko,Ẹsẹ-ifá,Àwujọ Yorùbá.

**RESUMO**
Ifá é uma parte importante da literatura oral iorubá. A sociedade iorubá tem muita fé nele. Não há nada sobre o qual Ifá não fale, começando pelos seres humanos, a relação entre marido e mulher, árvores, montanhas, rios, terra, plantas, pássaros, insetos, a relação com a natureza, as histórias dos deuses e vários animais. Ifá fala muito sobre vários animais selvagens; todos os animais sobre os quais Ifá fala são usados como provérbios para os humanos. Muitas vezes, Ifá fala sobre animais e os apresenta como pessoas. Por exemplo, eles podem ter problemas para ir ao Babalawo para ir ao templo, e seus problemas podem estar relacionados a sacrifícios e assim por diante. Ifá é repleto de vários conhecimentos místicos. Ifá nos conta sobre a história da origem dos animais e também permite que os caçadores conheçam os nomes desses animais e o papel que desempenham na sociedade humana. O que esta obra mais persistentemente faz é apresentar o que Ifá diz sobre os animais. Como os apresenta como outra criação de Deus na sociedade. As categorias examinadas neste trabalho são a história dos animais como retratada em Ifá, a representação dos animais em termos de seu comportamento e as lições que eles ensinam à sociedade.

**PALAVRAS-CHAVE**
Literatura, Animais, Ifá, Sociedade Iorubá.

* Department of Yorùbá, Adéyẹmí Federal University of Education, Oǹdó. E-mail: funmifayomiajayi@gmail.com

**Ìfáárà**

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onímọ̀ ni wọ́n ti ṣiṣẹ́ lọ́kàn-ò-jọ̀kan lórí Ifá gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan gbòógì lára Lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, èyí tí wọ́n kà kún pàtàkì láwùjọ. Irú èrò yìí hàn nínú Ọlátúnjí (1984:110) tó sọ pé:

> of all the methods of divination employed by the Yoruba, Ifá is regarded as the most important and the most reliable (Nínú gbogbo ọ̀nà tí Yorùbá ń gbà láti fi yẹ nǹkan wò, Ifá ni wọ́n gbà pé ó ṣe é gbẹ́kẹ̀lé tí ó sì ṣe pàtàkì jù lọ).
>
> Ohun tí Ọlátúnjí ń sọ nínú àyọlò òkè yìí ni pé Ifá kì í ṣèké, ọ̀gangan ọ̀nà ni Ifá máa ńtọ̀ láì fi igbá kan bọ ọ̀kan nínú.

Iṣẹ́ Abímbọ́lá (1968, 1975, 1976, 1997a àti 1977b) jẹ́ yaágbó yaájù lórí Ifá. Ó ní àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé Ifá ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọgbọ́n àti òye, ó ní wọ́n gbàgbọ́ pé ohunkóhun tí wọ́n bá ti gbọ́ láti ọ̀dọ̀ Ifá jẹ́ ìmọ̀ràn pàtàkì tí ènìyàn kò gbọdọ̀ fojú fò dá. Àṣáolú (1981:79) sọ pé kò sí ohun tí Ifá kò sọ̀rọ̀ lé lórí, ó ní láti orí ènìyàn títí ó fi dé àwọn iṣẹ́ ọwọ́ Olódùmarè mìíràn. Ó ní kò sí ẹranko kan tàbí ẹyẹ kan, tàbí igi oko, omi, ìwà, ìṣe, ìrísí àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Gẹ́gẹ́ bí mo ṣe sọ síwájú pé òwe ni Ifá ń pa, nítorí pé gbogbo ohun tí Ifá sọ nípa àwọn ẹranko wọ̀nyí ni ó fi mú wọn hùwà bí ènìyàn. Àwọn náà ń rúbọ, Ifá sì tún fi àwọn kan hàn gẹ́gẹ́ bí babaláwo. Oríṣiríṣi ọ̀nà ni Ifá fi gbà gbé àwọn ẹranko kalẹ̀. Ifá rí àwọn ẹranko gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ ọwọ́ Olódùmarè mìíràn tí ìṣesí wọn jọra pẹ̀lú ẹ̀dá ènìyàn, ìdí nìyí tí àwọn Yorùbá fi máa ń sọ ìpèdè bíi “Ìṣènìyàn nìṣẹranko”.

Àwọn ohun mìíràn tí Ifá tún jẹ́ kó yé wa ni pé àwọn ọmọ ẹ̀dá adáríhurun ní àṣẹ àti agbára lórí àwọn ẹranko. Tíọ́rì tí a lò fún iṣẹ́ yìí ni tíọ́rì Ìfìwádìí-sọ̀tumọ̀-èrò ọkàn.

**Tíọ́rì Ìfìwádìí-Sọ̀tumọ̀-Èrò ọkàn**

Ajíbádé (2003) nínú iṣẹ́ rẹ̀ sọ pé tíọ́rì ìfìwádìí sọ̀tumọ̀ (Hermeneutics) jẹ́ láti ara tíọ́rì ìfojú-inú-wo-ẹ̀mí ara nǹkan (Phenomenology). Onímọ̀ yìí sọ pé ìtumọ̀ iṣẹ́ kan kò dá dúró fúnra rẹ̀ àti pé kì í ṣe èdè ló ń fi èrò àti ìrírí wa ní ìtumọ̀ tí iṣẹ́ bá ni, ló bí tíọ́rì ìfìwádìí-sọ-ìtumọ̀. Husserl sọ pé tí a bá fojú inú wo nǹkan ló lè mú kí àjọṣepọ̀ wà láàrin èrò ọkàn wa àti ohun tí à ń fojú inú wò. Èyí túmọ̀ sí pé ojú tí a fi ń wo iṣẹ́ àti èrò inú wa ló lè fún iṣẹ́ ní ìtumọ̀ tó jinlẹ̀ tí kò jẹ mọ́ ẹ̀sìn. Eagleton (1983:73) ṣàlàyé pé:

Hermeneutics sees history as a living dialogue between present and future and seeks patient to remove obstacles to this endless mutual communication. (Ìfìwádìí sọ̀tumọ̀ máa ń rí ìtàn gẹ́gẹ́ bí ìtakùrọ̀sọ láàrin ohun tí ó ń lọ lọ́wọ́ àti ọjọ́ iwájú, ó sì máa ńṣaápọn ní pẹ̀lẹ́pùtù láti mú ìdínà tó wà láàrin àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ kúrò)

Eléyìí fi hàn pé tíọ́rì yìí ń ṣe àmúlò ìtàn inú àwùjọ láti lè ní òye àti ìmọ̀ tó pé lórí ohun tí à ń ṣe ìwádìí lé lórí nínú irú àwùjọ bẹ́ẹ̀. Ohun tí ó ń tún ṣàlàyé láti jẹ́ kó yé wa nínú tíọ́rì yìí gẹ́gẹ́ bí Ajíbádé (2003) ṣe sọ ni pé gbogbo ohun tó wà láyé kò wà lásán bí kò ṣe pé wọ́n ní nǹkan ṣe pẹ̀lú ènìyàn.

Davey (1999:4-5) onímọ̀ yìí sọ pé a lè pín afọ̀ sí ọ̀nà mẹ́ta. Ó ní ọ̀nà kìíní ni ọ̀rọ̀ inú bíbélì àti àtúpalẹ̀ àwọn afọ̀ ajẹmẹ́sìn tí wọ́n lò ó fún ní ọ̀rìndínkejìlélógún, ọ̀nà kejì ni pé wọ́n fi ń ṣe àtúpalẹ̀ àwọn nǹkan tó jẹ mọ́ àṣà àti ọ̀rọ̀ ìbára-ẹni-gbépọ̀, ọ̀nà kẹta ni èyí tí wọ́n fi ń ṣe àtúpalẹ̀ àwọn nǹkan tó jẹ mọ́ ìtàn àti àṣà tí a lè fojú rí. Èyí wá ń fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé bí tíọ́rì yìí ṣe wúlò fún lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ náà ni ó wúlò fún ṣíṣe àyẹ̀wò lítíréṣọ̀ alohùn pàápàá jù lọ ẹsẹ-Ifá tí a fẹ́ gbé yẹ̀wò nínú iṣẹ́ yìí.

Ìtàn Àwọn Ẹranko bí ó ṣe hàn nínú Ẹsẹ-Ifá

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ síwájú pé oríṣiríṣi nǹkan ni Ifá jẹ́ ká mọ̀ nípà àwọn ẹranko. Odù Ifá ògbèyẹ̀kú sọ nípa bí kìnnìún ṣe jẹ́ ọba àwọn ẹranko nínú àwùjọ wọn. Ó ní:

Ògbèyẹ̀kú ni baba àmúlù
Orógbó mo rótọ̀ ni baba alákẹ̀dun
Olóólà tó kọ ohun kì í kọ ìgbín
Olóólà tó bá kọ̀gbín kò gbọdọ̀ kọ alábahun
A dífá fún kìnnìún ẹranko a fìtọ̀ gbajù
Tí ó wá fìtọ̀ gbajù ilé baba rẹ̀.

Tíọ́rì ìfìwádìí-sọ̀tumọ̀ tọ́ wa sọ́nà láti ṣe ìwádìí nípa àyọlò ẹsẹ-Ifá yìí. Ìwádìí sọ fún wa pé baba ńlá kìnnìún tí ó ti ní ìjù nígbà ìṣẹ̀m̀báyé èyí tó jẹ́ pé gbogbo ẹranko ni ó mọ̀. Nígbà tí ó pẹ́ bàbá kìnnìún kú, kìnnìún dámọ̀ràn pé òun ní láti gorí ìtẹ́ baba òun, gbogbo àwọn ẹranko yòókù kọ̀, wọ́n ní kò lè ṣe é ṣe, àwọn bí i ẹfọ̀n, erin, ẹkùn, egbin, ìmọ̀dò, àjàǹtálá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Gbogbo wọn foríkorí pé kì í ṣe lójú àwọn ni ọmọ kìnnìún yóò ṣe tún gorí ìtẹ́ baba rẹ̀. Wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí í gbógun ti kìnnìún àti àwọn ìran rẹ̀ yòókù. Kìnnìún wá tọ Ọ̀rúnmìlà lọ lókè ìgẹ̀tì, Ọ̀rúnmìlà ní kí ó rúbọ, ó ní kí ó lọ tọ́jú ọtí amúwàgún, owó àti àkùkọ adìẹ mẹ́rìndínlógún àti àgbò, kó sì rú ẹbọ wọ̀nyí. Nígbà tí ó rúbọ tán, tí Ọ̀rúnmìlà bá a ṣe ètùtù, ó mu ọtí yìí pẹ̀lú ewé Ifá tí ó lọ̀ pẹ̀lú rẹ̀, ó fi síi, ó mú ìyẹ̀rẹ̀ Ifá ó tẹ̀ ẹ́ sí i, ó sì mú ìfọ̀rọ̀kànsì, ó ní kó máa mú díẹ̀díẹ̀.

Ọ̀rúnmìlà sọ fún kìnnìún pé àdúgbò tí ó bá wà tí ìtọ̀ bá ti ń gbọ̀n ọ́n, kí ó máa tọ̀ yí ibẹ̀ po, kí òun náà sì wà ní ààrin ìtọ̀ yìí, gbogbo ẹranko tí ó bá ti fẹ́ ṣe Kìnnìún ní ìjàm̀bá ni ìjàm̀bá yóò máa ṣe. Nígbà tí ìjàm̀bà yìí pọ̀ jù fún àwọn ẹranko ni gbogbo wọn bá panupọ̀ wọ́n sì fi Kìnnìún jọba. Báyìí ni gbogbo wọn gba Kìnnìún lọ́ba jákèjádò. Bí ẹkùn ṣe lágbára tó tí gbogbo ènìyàn mọ̀-ọ́n ní alágbára nínú àwọn ẹranko kò jẹ́ kóyán Kìnnìún kéré. Nítorí náà gbogbo ẹranko ni ó gba Kìnnìún ní ọba gẹ́gẹ́ bí ẹsẹ-Ifá ògbèyẹ̀kú ṣe sọ.

Bákan náà ni ẹsẹ-Ifá jẹ́ ká mọ ìtàn bí Erin àti Ẹfọ̀n ṣe lọ́lá láwùjọ àwọn ẹranko. Odù Ifá ọ̀kànràn méjì ẹsẹ èkejì sọ pé:

Arọ̀jọrọ̀jọ ìjòkùn
A díá fún erin
Tí í ṣe ọmọ Olúigbó
A díá fún Ìràngan mọ̀tẹ̀
Wọ́n ní kí erin ó rúbọ
Kí erin ó lè lọ́lá
Wọ́n ní kí ẹfọ̀n ó wọ̀yẹ̀
Kí ó lè ba à níyì…
Erin gbọ́
Ẹfọ̀n wòye…
Ọwọ́ erin tẹ ọlá
Nítorí ó rúbọ ńláńlá
Ọwọ́ ẹfọ̀n tẹ iyì
Nítorí ó rúbọ púpọ̀ púpọ̀ rẹgẹdẹ

Ìtàn ni ẹsẹ-Ifá yìí rọ́ fún wa, kí a ba lè mọ̀ pé ẹbọ tí àwọn ẹranko ńláńlá méjì yìí rú ni ó jẹ́ kí wọn ó lọ́lá, kí wọn ó sì níyì. Yàtọ̀ sí èyí, ẹsẹ-Ifá yìí jẹ́ ká mọ̀ pé àwọn ẹranko méjèèjì yìí gbọ́nran sí Ifá lẹ́nu. Ẹ̀kọ tí èyí kọ́ ọmọ aráyé ni wí pé kí a máa ṣe ohun tí ó bá yẹ lásìkò. Ẹsẹ-Ifá tún jẹ́ ká mọ ìtàn tí ó rọ̀ mọ́ Òkété àti Ọká. Ìdí tí ó fi jẹ́ èèwọ̀ fún Ọká láti pa Òkété jẹ. Ifá ní:

A díá fokete
Tí ń lọ tẹ Ọká nífá
Ọká bóo bá gbáwo mì
Ibi lọ ṣe
Èrìgì àlọ̀
Ọká bóo bá pEwúsà wà á kú
Ọká bóo gbáwo mì
Ibi lo ṣe

Ẹsẹ-Ifá yìí jẹ́ ká mọ̀ pé Ọká kì í ṣe alágbára ẹranko láàrin àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀, ọwọ́ rẹ̀ kò sì tó ire. Ọká lọ bá Ọ̀rúnmìlà pé kí ni kí òun ṣe kí òun lè ba lágbára, kí ire lè ba tẹ òun lọ́wọ́, kí ohun tí òun yóò jẹ lè máa wá bá òun, kí ebi má ba lu òun pa. Ọká lọ bá Òkété tí ó jẹ́ babaláwo yánrányánrán nígbà náà pé kí ó wá tẹ òun nífá. Ó sọ fọ́ká pé ara rẹ̀ yóò dá, ebi kò sì ní pa á mọ́. Òkété gbé àṣẹ lé e lọ́wọ́, ó ní ṣùgbọ́n kan tí ó wà níbẹ̀ ni pé kò gbọdọ̀ na àṣẹ yìí sí babaláwo tàbí ẹni tí ó bá ń tẹfá pàápàá sí òun Òkété.

Nígbà tí ó di ọjọ́ kan ni Ọká bá na àṣẹ rẹ̀ sí Òkété ṣùgbọ́n kí Òkété tó kú ni ó ti fi Ọká ré pé nígbàkugbà tí ó bá ti pa Òkété kò ní rá mọ nínú tí wọn yóò fi pa Ọká náà. Ìdí rẹ̀ tí ó fi jẹ́ pé tí Ọká bá pa Òkété kò lè tó ọjọ́ kejì tàbí ó pẹ́ jù ọjọ́ kẹta kí wọ́n tó pa òun náà. Síwájú sí i, nínú ìwòrì méjì ni a ti rí ẹsẹ-Ifá tí ó sọ ìtàn nípa Ẹkùn àti awọ rẹ̀.
Ẹsẹ-Ifá yìí sọ pé:

A díá fún kékeré ọdẹ àti òfinràn Òkọ̀jà
Wọ́n ń lọ rè é dẹgbó ìwòrì ní ọ̀sán gangan
Wọ́n ní kí wọn ó mọ́ lọ dẹ igbó náà

Àfi bí wọ́n bá rúbọ
Ṣùgbọ́n òfinràn òkọ̀jà kò gbọ́…
Kíjìpá ẹbọ ìwòrì tí kò rú náà
ni ẹkùn ń gbé kiri di òní
(Abímbọ́lá 1975:19)

Ohun tí Ifá yìí ń sọ fún wa ni pé kékeré ọdẹ àti òfinràn Òkọ̀jà jẹ́ ọ̀rẹ́ tí ó máa ń dẹ igbó ẹran. Wọ́n pinnu láti lọ dẹ ìgbẹ́ ní igbó ìwòrì, ṣùgbọ́n kí wọ́n tó lọ, wọ́n lọ fi ọ̀rọ̀ náà lọ babaláwo. Babaláwo kìlọ̀ fún wọn kí wọ́n má ṣe lọ láì jẹ́ pé wọ́n rúbọ, òfinràn Òkọ̀jà kọ̀ jálẹ̀ kò rúbọ yìí. Bí ó ṣe di ọ̀sán gangan ọjọ́ kan ni ó múra tí ó gba igbó ìwòrì lọ. Bí ó ti dé inú igbó ìwòrì ni àwọn iwin igbó ìwòrì bá da kíjìpá wàáka bò ó lára, bí òfinràn Òkọ̀jà ṣe di ẹkùn nìyí. Ìwádìí sọ fún wa pé kíjìpá ẹbọ ìwòrì tí kò rú náà ni Ẹkùn ń gbé kiri di òní.

Àfihàn Àwọn Ẹranko Nínú Ẹsẹ-Ifá

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìwà àwọn ẹranko ni ẹsẹ-Ifá fi hàn. Ó jẹ́ ká mọ bí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ṣe ń hùwà láàrin àwọn ẹlẹgbẹ́ wọn.
Ọ̀kẹ́rẹ́: Ifá fi Ọ̀kẹ́rẹ́ hàn gẹ́gẹ́ bí olófòfó tí ẹnu rẹ̀ kò bò. Kò ní àṣírí kankan rárá. Ẹ̀bá ọ̀nà ni Ọ̀kẹ́rẹ́ ń gbé. Ifá jẹ́ ká mọ̀ pé gbogbo ayé ló tò fún pé ìyàwó òun bímọ púpọ̀ àti wí pé ilé òun kún fọ́fọ́. Ifá ní:

Ẹnu òfóró ní í pòrófó
A díá fún ọ̀kẹ́rẹ́…
Wọ́n ní kí ọ̀kẹ́rẹ́ ṣọ́ra

Nítorí pé ẹnu rẹ̀ kò bò
Wọ́n ní kó mọ́ mọ́ ọ fi gbogbo ohun
tí ó bá rí sọ fún èèyàn mọ́…
Ó ní ọ̀kẹ́rẹ́ bímọ méjì
Ilé kún tẹ́tẹ́ẹ́tẹ́…

A rí Ọ̀kẹ́rẹ́ bí ẹranko tó kọ ìkìlọ̀, ó kọtí ọ̀gbọin sẹ́bọ tí wọ́n ní kí ó rú. Yàtọ̀ sí èyí Ọ̀kẹ́rẹ́ tún fi ẹnu ara rẹ̀ kó bá ara rẹ̀. Ẹ̀kọ́ tí ìwà Ọ̀kẹ́rẹ́ kọ́ àwùjọ ni pé kò dára kí ènìyàn ó máa to ẹjọ́ jù nítorí pé bí ènìyàn bá ń tojọ́ àtòjù kò ní mọ ìgbà tí yóò to ti ara rẹ̀.
Ìwọ̀ntúnwọ̀nsì ni ó yẹ gbogbo nǹkan tí ẹ̀dá bá ń ṣe nílé ayé.
Ìtàn mìíràn tí ifá tún jẹ́ ká mọ̀ nípa Ọ̀kẹ́rẹ́ ni pé,Òun àti Ọká jẹ́ ọ̀rẹ́ tímọ́tímọ́,ọ̀rẹ́ kòríkòsùn sì ni wọ́n pẹ̀lú,ẹsẹ-ifá ògúndá-kànrán sọ pé:

Ògúndá lawo à ń làgbá
Ọ̀lọ̀kànràn lawo à ń lùgèdè
Ogun tá à bá lagbá lùgèdè sí
Ó ti kúrò lógun àdájà
Ó ti dogun tọ́ba ń gbọ́ tí í ránṣẹ́ sí tilé toko
A díá fún Ọ̀kẹ́rẹ́ tó gba seeséè,Obinrìn Ọká
Ó sọ pé mo gbà á tèfètèfè seeséè…….( Babaláwo Ifáníyọ̀ okùnọlá)

Ibí yìí ni a ti dá ifá ògúndá lọ́tùn ún ,Ọ̀kànràn lọ́wọ́ òsì,ìtàn tó rọ̀ mọ́ ẹsẹ ifá yìí ni pé Ọ̀kẹ́rẹ́ jẹ́ ọ̀rẹ́ tímọ́tímọ́ ejò ọká,kò sí ohun tí wọn kìí sọ fún mí ara wọn,ọ̀rẹ́ ìmùlẹ̀ ni wọ́n,èyí ni pé tí ọ̀rẹ́ bá pẹ́ a máa di ìyekan.Ọ̀rẹ́ wọ́n dùn dé bi pé nígbà tí Ọká fẹ́ rin ìrìn àjò,ó wá fi obìnrin rẹ̀ ti Ọ̀kẹ́rẹ́,ó ní kó bá òun mójú tó ilé,ṣùgbọ́n kò pẹ́ kò jìnnà tí Ọ̀kẹ́rẹ́ fi gba ìyàwó Ọká.Seeséè wá sọ fún Ọ̀kẹ́rẹ́ pé ọkọ òun kò ní pẹ́ dé láti ìrìn àjò,ó sì ní oró,nítorí náà ó lè dá wàhálà sílẹ̀ tó bá dé.Ọ̀kẹ́rẹ́ wá sọ fún seeséè pé kó má fòyà,wí pé àwọn yóò gba orí igi lọ,ìgbà tí ọká dé nítòótọ́ seeséè àti ọ̀kẹ́rẹ́ gba orí igi lọ,orí igi yìí ni wọ́n ń gbé.Ọká wá bẹ̀rẹ̀ sí wá wọ́n káàkiri,bí ọká bá ti ń gbúròò wọn yóò máa ró kẹ̀kẹ̀,ìdí nìyí tí àwọn bàbá wa fi máa ń sọ pé ibi tí a bá ti rí Ọká tí ó bá ti ń ró kẹ̀kẹ̀ a jẹ pé ọ̀kẹ́rẹ́ wà láàrin ibẹ̀ ni.Ìgbà tí ó di ọjọ́ kan Ọká tún ń ṣọ́ Ọ̀kẹ́rẹ́ bí ó ṣe ń ṣe akọ si pé òun gba ìyàwó Ọká tèfètèfè,bẹ́ẹ̀ ni Ọ̀kẹ́rẹ́ ń bẹ́ láti orí igi kan sí èkejì,kò pẹ́ kò jìnnà bí ìtàkùn ṣe kọ́ Ọ̀kẹ́rẹ́ lẹ́sẹ̀ nìyí tí ó fi bọ́ sẹ́nu Ọká,ìdí nìyí tí àwọn Yorùbá fi máa ń sọ pém"tí ìtàkùn kò bá já,ọwọ́ ò le tẹ Ọ̀kẹ́rẹ́ nígbó". Ọká wá bẹ̀rẹ̀ sí fi ìyà jẹ Ọ̀kẹ́rẹ́,ìdí abájọ náà nìyí tí a fi máa ń gbọ́ ìpèdè bíi"dán án wò ló bí ìyà Ọ̀kẹ́rẹ́"ibí yìí ni a ti dá Ògúndá ní ọwọ́ ọ̀tún,Ọ̀kànràn lọ́wọ́ òsì.
Àfẹ̀rẹ̀bòjò: Ifá fi ẹranko yìí hàn gẹ́gẹ́ bí ẹranko tí ó tóbi. Ifá jẹ́ ká mọ bí ilé àfẹ̀rẹ̀bòjò ṣe máa ń tóbi tó. Àfẹ̀rẹ̀bòjò jẹ́ ẹranko tí ó máa ń ṣe ilé rẹ̀ bí i ti ọmọ ènìyàn. Ifá ní:

Àfẹ̀rẹ̀bòjò ní í walée tiẹ̀ wòǹdoro wòǹdoro
Ilé àfẹ̀rẹ̀bòjò gboyè ó gbàtẹ́
Bẹ́ẹ̀ ni kò gbọdọ̀ jọba

Àlàyé ohun tí Ifá ń ṣe fún wa nípa àfẹ̀rẹ̀bòjò ni pé ilé àfẹ̀rẹ̀bòjò dàbí ìtẹ́ ọba, kò sí ohun tí wọ́n wá dé ibẹ̀ tí kò sí níbẹ̀.A tilẹ̀ gbọ́ nínú ìwádìí láti ẹnu àwọn ọdẹ pé oríṣiríṣi nǹkan bí ohun èlò tí ọmọ ẹ̀dá máa ń lò ni ó kún inú ibùgbé Àfẹ̀rẹ̀bòjò.Èyí fi hàn pé ìṣesí àfẹ̀rẹ̀bòjò jọ ti ènìyàn. Ẹ̀kọ́ tí a lè rí kọ́ lára ẹranko yìí ni wí pé akínkanjú ẹranko tí kì í ṣe ọ̀lẹ ni nítorí pé ọwọ́ ni ó fi máa ń wa ilẹ̀ ilé tí ó ń gbé. Kì í ṣe wí pé yóò wa ilẹ̀ nìkan ṣùgbọ́n yóò yọ yàrá lóríṣiríṣi sínú ihò ilẹ̀ náà.
Ẹkùn: Ifá fi ẹkùn hàn gẹ́gẹ́ bí onígbèràga ẹranko, wọ́n ní kó rúbọ nítorí oko ọdẹ tí ó ń lọ, kí ó má ba ko elénìní lọ́nà. Ẹkùn ní ta ni yóò ṣe elénìní òun ẹkùn. Ẹsẹ-Ifá sọ pé:

Gbòǹgbò ṣe wọ̀rọ̀kọ̀ fi wọ̀rọ̀kọ̀ jánà
A díá fẹ́kùn
Níjọ́ tó ń lọ oko ọdẹ…
Wọ́n ní kí ó rúbọ elénìní
Ẹkùn ní ta ni ó ṣe elénìní òun Ẹkùn
Ó ní òun ò ní í rú…

Ẹsẹ-Ifá yìí jẹ́ ká mọ̀ pé onígbèràga ni ẹkùn ṣùgbọ́n èṣù kọ́ ọ lọ́gbọ́n, nígbà tí ebi pa á, kíá ni ó lọ rúbọ. Ó gbẹ́kẹ̀lé agbára rẹ̀ ṣùgbọ́n ẹ̀tẹ́ ló bá bọ̀. Ẹ̀kọ́ tí èyí kọ́ àwùjọ ni wí pé kí a má ṣe gbẹ́kẹ̀lé agbára wa nìkan àti wí pé kí a má jọ ara wa lójú, kí a sì mọ̀ pé Ọlọ́run nìkan ni ó ni agbára.

Ẹdun/Ọ̀bọ: Ifá fi ẹdun àti àáyá hàn gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe lè sáré tó. Ifá jẹ́ ká mọ̀ pé ẹdun kò lè sáré tó àáyá nítorí aré orí igi ni ẹdun mọ̀ ọ́n sá. Ifá tún jẹ́ ká mọ̀ pé àwọn ẹranko méjèèjì yìí fẹ́ràn láti máa ya àgbàdo inú oko láti jẹ. Ifá ní:

Aré ló bẹ́dun ń lẹ̀ Ẹdun ò mọ̀ ọ́n sá
A díá fún Ẹdun
Ẹdun tí í ṣọmọ ìyá àáyá
Àáyá fò fẹ̀rẹ̀ ó dorí ìgbá
Ẹdun ta fere ó dorí igi…
Ṣùgbọ́n ní ọjọ́ kan
Ẹdun àti àáyá wá jalè
Wọ́n lọ jí àgbàdo ya lóko olóko
Àáyá ló kọ́kọ́ rí olóko
Ló bá fò fẹ̀rẹ̀ gun igi ìgbá
Nígbà tí Ẹdun ó fi wí pé òun fò
Olóko ti dé

Ohun tí ẹsẹ-Ifá yìí ń sọ ni pé àáyá mọ eré sá ju ẹdun lọ. Yàtọ̀ sí èyí, ẹsẹ-Ifá yìí fi hàn pé àáyá gbọ́n púpọ̀, ó sì tún ní ìfura ju ẹdun lọ. Ẹ̀kọ́ tí ẹsẹ-Ifá yìí fi àwọn ẹranko méjì yìí kọ́ wa ni pé, a gbọ́dọ̀ máa kíyèsára, kí a sì máa ṣọ́ra nípa irú ọ̀rẹ́ tí a gbọ́dọ̀ máa bá ṣepọ̀.

Ajá: Ajá jẹ́ ẹranko tí Ifá fihàn gẹ́gẹ́ bí aláìgbọràn àti olóríkunkun. Ifá kì í nílọ̀ pé kí ó yẹra fún ibi tí a kò peni sí, ṣùgbọ́n ajá ṣe àìgbọràn sí ìkìlọ̀ yìí, ó sì lọ sí ibi tí a kò pè é sí. Ẹsẹ-Ifá ọ̀kànràn méjì ní:

Bẹ́lẹ́bọ ò peni…
Ọ̀ràn tí ò sunwọ̀n
Konko ń ṣojú
A díá fún Taǹpèọ̀
Tí ó gba kùmọ̀ sátàrí
Wọ́n ní kí Taǹpèọ̀ ó ṣọ́ra o

Kí ó mọ́ lọ síbi tí wọn ò pè é sí kò gbọ́…
Kùmọ̀ ni wọ́n kó tì í
Ó sì jẹ ọ̀pọ̀ ìyà níbẹ̀

Nínú ẹsẹ-Ifá òkè yìí, a ri pé àdàpè ajá ni Taǹpèọ̀. Ohun tí ojú aláìgbọràn ń rí ni ojú ajá rí níbí, bí a wí fọ́mọ ẹni a gbọ́. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹ̀dá ọmọnìyàn láwùjọ náà ni ó jẹ́ pé ìwà àìgbọràn ti

sún wọn dé oko gbèsè, tí ó sì ti rán wọn ní ìrìn àjò ọ̀sán gangan. Òwe ni láti lè kọ́ ẹ̀kọ́ lára wọn. Ẹ̀kọ́ tí a rí fàyọ nínú ẹsẹ-Ifá yìí ni pé àìgbọ̀ràn kò dára àti wí pé
kí a má ṣe máa kọ ìkìlọ̀ àwọn àgbà tàbí àwọn tí ó juni lọ.

Ìwúlò Àwọn Ẹranko Láwùjọ

Ọjọ́ ti pẹ́ tí àwọn ẹranko ti ń gbé pẹ̀lú ẹ̀dá ènìyàn láwùjọ, ṣùgbọ́n Ọlọ́run fi ènìyàn ṣe olórí gbogbo nǹkan abẹ̀mí yòókù lórí eèpẹ̀. Ẹsẹ-Ifá kan tilẹ̀ jẹ́ kó yé wa pé ipa tí àwọn ẹranko ń kó láwùjọ kò kéré rárá. Ẹsẹ-Ifá Ọ̀sá méjì ṣàlàyé ìwúlò ìwo ẹfọ̀n fún ẹni tí ojú ọmọ ń pọ́n, ó ní:

Pọ̀ọ̀kọ́ ní idi…
A díá fún malámalá
Tí ń sunkún ọmọ yode òge
Wọ́n ní ó rúbọ nítorí ọmọ
Wọ́n ní ó mú ìwo ẹfọ̀n
Kó kùn-ún lósùn
Kó gbé e pọ̀n bí ọmọ
Kí ó máa kọrin fún un bí ọmọ
Ó sì ṣe bẹ́ẹ̀
Ó sì bí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ

Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ẹfọ̀n jẹ́ ká mọ̀ pé ó lè ṣọmọ fún àgàn tí ń wá ọmọ níwọ̀n ìgbà tí ó bá ti rúbọ tí kò sì kọtí ọ̀gbọin sẹ́bọ, ó di dandan kí ìbéèrè rẹ̀ ó wá sí ìmúṣẹ. Ṣàṣà ni àwọn ẹranko igbó tí àwọn ẹ̀dá alàààyè kì í jẹ àyàfi tí ó bá jẹ́ èèwọ̀ fún ìran, ẹ̀yà tàbí ti ẹ̀sìn kan. Wọ́n ń jẹ ẹran ara ẹranko fún oúnjẹ, wọ́n ń lo awọ ara wọn láti fi ṣe oríṣiríṣi oògùn fún ìwòsàn ara. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹ̀yà ara ẹranko la lè fi ṣe aájò fún
àlàáfíà àti ẹ̀mí gígùn àwọn ọmọnìyàn, bí àpẹẹrẹ eyá jẹ́ ẹranko tí wọ́n máa ń lo ẹyin ojú
rẹ̀ láti fi ṣe oògùn ìgboyà tàbí agbára fún ẹni tí àyà rẹ̀ bá ń já pàápàá jù lọ fún àwọn ọmọdé.

Yàtọ̀ sí jíjẹ àti lílò fún ìṣègùn, àwọn ẹranko bíi ràkúnmí, ẹṣin àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ tún wúlò fún kíkó ẹrù àti gígùn lọ sójú ogun láyé àtijọ́. Bákan náà ni a tún máa ń kó wọn sínú ọgbà ẹranko fún wíwò àwọn ènìyàn pàápàá jùlọ fún àwọn tí kò bá dá àwọn ẹranko wọ̀nyí mọ̀ yàtọ̀ síra.

**Àgbálọgbábọ̀**

A ti wo ohun tí Ifá sọ nípa àwọn ẹranko, bákan náà sì ni ojú tí àwọn ènìyàn fi ńwo àwọn ẹranko láwùjọ, ẹ̀kọ́ tí à ń kọ́ lára àwọn ẹranko àti ìwúlò wọn láwùjọ. Ẹsẹ-Ifá tún jẹ́ ká mọ oríṣiríṣi ìtàn tí ó rọ̀ mọ́ ẹranko kọ̀ọ̀kan àti ìdí tí ó fi jẹ́ pé kìnnìún ni ọba àwọn ẹranko. Ifá ni ó jẹ́ ká mọ̀ pé Erin ni ó lọ́lá jùlọ láàrin àwọn ẹranko àti wí pé ìṣẹ̀dá rẹ̀ yàtọ̀ sí àwọn ẹranko igbó yòókù. Ìdí nìyí tí Yorùbá fi máa ń fi orúkọ erin pe ọlọ́lá kan tí ó bá kú láàrin ìlú. Ju gbogbo rẹ̀ lọ ẹsẹ-Ifá ni ó jẹ́ ká mọ̀ pé àjọṣepọ̀ tí ó gúnmọ́
wà láàrin ènìyàn àti ẹranko.

## Àkójọpọ̀ Ìwé

Abímbọ́lá, W. (1975). *Sixteen Great Poems of Ifá.* UNESCO.
Abímbọ́lá, W. (1977). *Ifa Divination Poetry.* London: New York, NOK.
Abímbọ́lá,W.(2004). *Àwọn Ojú odù mẹ́rìndínlógún*. Ìbàdàn: University Press Plc.
Abímbọ́lá, W. Abímbọ́lá,W(2006). *Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ẹnu Ifá. Apá Kejì*. Ìbàdàn: University Press Plc.

Bascom.W,(1969).Ifá divination &communication between Gods and Men in West
Africa India.University Press,Bloomington.
Eagleton, T. (1983). *Literary Theory:* An Introduction. New York: Brazil Blackwell Publishers Ltd.
Agboọlá,F.(1969).*Ojúlówó Oríkì Ifá.Apá kìn-ín-ni*. Lagos:Project Publication Limited.
Ọlátúnjí, O. (1984). *Features of Yorùbá Oral Poetry*. Ìbàdàn: University Press Ltd.
Àṣáolú, Y. (1981). *Ìwé Ìléwọ́ Ifá Fún Àwọn Akẹ́kọ̀ọ́*. Iléṣà: Fátírègùn Press and Publishing Co. (Nig) Ltd.

Recebido em: 23/02/2025
Aceito em: 24/06/2025

**Para citar este texto (ABNT):** ÀJÀYÍ, Fúnmiláyọ̀ Tèmítọ́pẹ́ Àjàyí. Àfihàn Ohun tí Ifá sọ Nípa Aṣàyàn Ẹranko Láwùjọ Yorùbá. *Njinga & Sepé:* Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras. São Francisco do Conde (BA), vol.5, nº Especial I, p. 235-242, jan./jun.2025.

**Para citar este texto (APA):** Àjàyí, Fúnmiláyọ̀ Tèmítọ́pẹ́. (jan./jun.2025). Àfihàn Ohun tí Ifá sọ Nípa Aṣàyàn Ẹranko Láwùjọ Yorùbá. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 5 (Especial I): 235-242.